ÈṢẸ MIRIAMU ATI AARỌNI
Numeri 12:1-16
ẸKỌ 100 – FUN AWỌN ỌDỌ

AKỌSORI: "Awọn alàgba ti o ṣe akoso daradara ni ki a kà yẹ si ọlá ilọpo meji"(1 Timoteu 5:17).

Yiyan Mose Si Ipò

Ni ọjọ ti Mose ri igbẹ ti n jó ninu iju Sinai, Ọlọrun yan an lati pada lọ si Egipti lati lọ mu awọn eniyan Rẹ jade kuro ni oko-ẹru. Ọpọlọpọ igba lẹyin eyi ni Ọlọrun ti jẹri si i pe yiyan Mose jẹ lati ọdọ Oun wá. O si ti mu ki ọpọlọpọ iṣẹ iyanu ṣe nipa ọrọ rẹ. Mose bẹru lati gbe ẹru iṣẹ ti o wuwo to bayii, nipa sisọ pe oun ko ni agbara tó lati sọrọ niwaju Farao. Oun nikan ṣoṣo ni Ọlọrun ti n fẹ rán lọ tẹlẹtẹlẹ ṣugbọn nigba ti o n tẹnu mọ ọn pe oun ko ni le sọrọ fun ọba, Ọlọrun sọ pe Aarọni le ba a lọ ki o si maa gba ọrọ sọ fun un. Wò ó bi ipè Mose ti ga rekọja ju ti Aarọni tó, nitori Ọlọrun wi pe kiki Mose nikan ni yoo gbọ́ ohun Oun, ti yoo si maa sọ ohun ti o tọ́ fun Aarọni lati sọ. "On ni yio si ma ṣe ogbifọ rẹ fun awọn enia: yio si ṣe, on o ma jẹ ẹnu fun ọ, iwọ o si ma jẹ bi Ọlọrun fun un" (Ẹksodu 4:16). Lẹyin ti Aarọni tilẹ tun di olori alufaa, Mose ni o n gba aṣẹ lati ọdọ Ọlọrun fun un nipa ohun ti yoo ṣe.

Miriamu Wolii Obinrin

A kò sọ nipa ipè Ọlọrun fun Miriamu ninu Iwe Mimọ́, ṣugbọn lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli ti la Okun Pupa já ti awọn ará Egipti si ti ṣegbé nipa pipada ti omi pada ti o bo wọ́n mọle, a tọka si i gẹgẹ bi wolii obinrin; o si kọ orin iṣẹgun; "Ẹ kọrin si OLUWA nitoriti o pọ̀ li ogo; ẹṣin ati ẹlẹṣin on li o bì ṣubu sinu okun" (Ẹksodu 15:20, 21). Ati ninu Mika 6:4, a kà pe, "Nitori mo ti mu ọ goke lati ilẹ Egipti wá, mo si rà ọ padà lati ile ẹrú wá; mo si rán Mose, Aarọni, ati Miriamu siwaju rẹ." Nipa bayii a mọ pe Ọlọrun ni O yan Miriamu pẹlu. Ṣugbọn Mose ni aṣaaju Israẹli sibẹ ẹni ti o n ba Ọlọrun rin timọtimọ ju lọ. O tọ́ ki gbogbo eniyan, pẹlu ẹgbọn rẹ ọkunrin ati obinrin bu ọlá fun un.

Igberaga

Ni ọjọ kan, Aarọni ati Miriamu gbagbe ipò ti wọn wà gẹgẹ bi oluranlọwọ fun Mose. Igberaga wọ inu ọkàn wọn, wọn ṣe ariwisi si Mose nitori iyawo ti o fẹ́. Ọlọrun ko sọ ohunkohun lodi si i, ki ni ṣe ti awọn eniyan wọnyii fi ara wọn si ipò lati dá ẹni irẹlẹ Ọlọrun yii ni ejọ? Ariwisi wọn ni pe, "Nipa Mose nikan ni OLUWA ha sọ̀rọ bi?"

Awọn eniyan a maa sọrọ bẹẹ nigba ti wọn ba n fẹ lati sọrọ èṣan si alufaa wọn. 'Ọlọrun ko ha tipasẹ awa naa sọ̀rọ bi?' 'Ṣe bi awa naa ni Ọrọ Ọlọrun pẹlu wa?' 'O ha jẹ ọranyan fun wa lati gbọran si ohun ti awọn alufaa n sọ fun wa?'

Ni tootọ ni wọn ni Ọrọ Ọlọrun, bi wọn o ba si fara balẹ kà á, i ba fi èṣẹ wọn hàn fun wọn. Ohun ti Bibeli wi ni yii: "Ẹ mã gbọ ti awọn ti nṣe olori nyin, ki ẹ si mã tẹriba fun wọn: nitori nwọn nṣọ ẹṣọ nitori ọkàn nyin, bi awọn ti yio ṣe iṣíro, ki nwọn ki o le fi ayọ̀ ṣe eyi, li aisi ibinujẹ" (Heberu 13:17); ati pe, "Awọn alàgba ti o ṣe akoso daradara ni ki a kà yẹ si ọlá ilọpo meji, pẹlupẹlu awọn ti o ṣe lãlã ni ọ̀rọ̀ ati ni kikọni" (1 Timoteu 5:17).

Irẹlẹ Mose

Dajudaju Mose ti fihan nipa iṣẹ iyanu ti Ọlọrun ti tipasẹ rẹ ṣe, pe Ọlọrun ni O ran an. Sibẹ oun ko gberaga tabi ki o gba ọlá fun ara rẹ. O ti fẹ lati kú dipo ki a pa awọn Ọmọ Israẹli run. O ti fi aafin Farao silẹ nibi ti o ti wà ni ipò ọba-lọla fun itẹ Egipti, nitori o fẹ lati gba awọn eniyan rẹ kuro ni oko ẹru. Gbogbo nnkan ti o ni ni o ti fi silẹ lati ran awọn ẹlomiran lọwọ; sibẹ ọpọlọpọ igba ni awọn Ọmọ Israẹli ti kùn si i. Nisisiyii, awọn ti wọn sun mọ ọn ju lọ tun gbe ara wọn ga si i. Ṣugbọn Mose ko jẹ sọrọ pada si wọn – ko tilẹ sọ ọrọ kan.

Mose jẹ eniyan ọlọkan tutu, gẹgẹ bi wolii nla kan ti n bọ wa. Ni ọjọ kan Ọlọrun sọ fun Mose pe "Emi o gbe wolĩ kan dide fun wọn lãrin awọn arakunrin wọn, bi iwọ; emi o si fi ọ̀rọ mi si i li ẹnu" (Deuteronomi 18:18). Peteru fi idi rẹ mulẹ ni ọjọ Pẹntekọsti (Iṣe Awọn Apọsteli 3:22) pe Jesu ni Wolii naa. Njẹ a le ri ifarajọ laaarin Mose ati Kristi ninu ẹkọ yii? A sọ bayii nipa Jesu, "Ẹni, nigbati a kẹgan rẹ, ti kò si pada kẹgan; nigbati o jìya ti kò si kilọ; ṣugbọn o fi ọ̀ran rẹ le ẹniti nṣe idajọ ododo lọwọ" (1 Peteru 2:23). Ati gẹgẹ bi awọn ara ile Mose ti kẹgan rẹ; a sọ asọtẹlẹ pe Jesu naa yoo jiya lati ọwọ awọn ti o sunmọ Ọn timọtimọ jù lọ; "Nitõtọ ọrẹ-iyọrẹ ara mi, ẹniti mo gbẹkẹle, ẹniti njẹ ninu onjẹ mi, o gbe gigisẹ rẹ si mi" (Orin Dafidi 41:9).

Etí Ọlọrun Ti N Gbọ́

Bi Mose ko tilẹ dá Miriamu ati Aarọni lohun, Ọlọrun tẹti si i. O fẹran Mose oninu-tutu ati onirẹlẹ nì. Lẹsẹkẹsẹ ni Ọlọrun pe awọn mẹtẹẹta lati wá si inu Agọ, si ibi idajọ. O wi fun Miriamu ati Aarọni pe, "Mose iranṣẹ mi. . . . . olõtọ ni ninu gbogbo ile mi." Oun kò fẹ ki ẹnikẹni sọrọ odi si i.

Ọlọrun ṣe alaye fun Aarọni ati Miriamu pe Mose ju wolii lọ. Ọlọrun a maa ba awọn wolii iyoku sọrọ ninu àlá ati iran, ṣugbọn O ti ba Mose sọrọ gẹgẹ bi 'ọrẹ si ọrẹ.' Ọlọrun si ti fi ogo Rẹ hàn fun Mose ju bi O ti fi han fun ẹnikẹni lọ. Nigba ti Mose lọ si ori oke lẹẹkeji lati gba Ofin, ogo Oluwa pọ lara rẹ to bẹẹ ti awọn eniyan naa ko le wo oju rẹ titi o fi fi iboju bo oju rẹ. Gbogbo eyi ni wọn mọ. Ọlọrun wa beere, "Njẹ nitori kili ẹnyin kò ṣe bẹru lati sọrọ òdi si Mose iranṣẹ mi?"

Ọlọrun ṣọ ẹṣọ lori awọn oloootọ iranṣẹ Rẹ, yoo si dá ẹnikẹni ti o ba huwa iwọsi si wọn lẹjọ. Awọn alufaa ti o bu ọla fun Bibeli ati gbogbo ẹkọ inu rẹ ni a yàn ti a si pe lati ọwọ Ọlọrun, bi a ba si kùn si wọn a n kùn si Ọlọrun ni. Wọn o jihin fun Ọlọrun fun awọn ẹkọ ti wọn n kọ eniyan, ti wa ni lati bu ọla fun ọrọ wọn, ki a si ṣe iranlọwọ fun wọn nipa igbọran wa. A ni lati maa bu ọla fun wọn ninu ifẹ, "nitori iṣẹ wọn" (1 Tẹssalonika 5:12, 13).

Awọn ti o n kùn si awọn aṣaaju wọn ki yoo lọ laijiya. Idajọ Ọlọrun lori Miriamu ni pe o di adẹtẹ. Wò bi arun yii ti buru tó ! Eyi yoo ya a kuro lara gbogbo awọn ti o fẹran. Diẹdiẹ ni iku maa n wá sori ẹni ti arun èṭè bá kọlu, ẹni ti arun yii bá mú ni lati dá wà fun ara rẹ, tabi ki o wà pẹlu awọn ẹlẹtẹ bi ti rẹ. Nigba ti ẹlomiran ba n bọ ni tosi o ni lati maa kigbe pé, "Alaimọ́, alaimọ́." Eyi ko ha i ṣe ijiya ti o ba ni lẹru fun kikùn ti Miriamu ati Aarọni kùn?

Ironupiwada

Kiakia ni wọn ronupiwada, Aarọni si bẹ Mose pe ki o gbadura fun un. O rẹ ara rẹ silẹ o si pe Mose ni "Oluwa mi." Aarọni mọ pe oun ti huwa aṣiwere ni riro pe ipò kan naa ni oun wà pẹlu Mose, o si pe ẹni ti oun ti ṣe iwọsi sí lati gbadura fun oun.

Mose ni ẹmi Kristi ninu rẹ ti o kun fun aanu nigba gbogbo. Kò sọ fun Miriamu pe, 'Eyi ni o tọ si ọ.' Ṣugbọn o ke pe Oluwa o si wi pe, "Ọlọrun, emi bẹ ọ, mu u lara dá nisisiyi." O gbadura kikankikan ati tọkantọkan, Ọlọrun si dahun. Lẹsẹkẹsẹ ti a ba ti ronupiwada ẹṣẹ wa, ti a si sọ fun Jesu pe a gba pe a ṣe buburu ni tootọ, Oun yoo wẹ gbogbo wọn nù patapata, a o si di mimọ́.

Ẹṣẹ buburu jayi ni Miriamu ati Aarọni dá; bi o tilẹ jẹ pe Ọlọrun ṣaanu, O si dahun adura Mose, O ni a ni lati sé e mọ́ ẹyin ibudo ni ọjọ meje nitori o jẹ alaimọ́ nitori ẹtẹ naa. Gẹgẹ bi ofin wọn, bi baba kan ba tẹ ọmọbinrin rẹ nipa titu itọ́ si ni oju, o ni lati jẹ́ alaimọ́ ni ọjọ meje. Wo o bi èṣẹ ti Miriamu ṣẹ ti tobi ju eyi lọ tó, njẹ ko tọ fun un lati jẹ alaimọ fun iye ọjọ bẹẹ, o kere tan? Ṣugbọn nigba ti akoko yii pe, a mu Miriamu lara dá, o si pada si ipò rẹ laaarin ibudo awọn Ọmọ Israẹli. Bayii ni a fi aanu hàn fun awọn ti wọn ronupiwada iwa aitọ ti wọn hù.

AWỌN IBEERE

1. Ta ni aṣaaju Israẹli?
2. Bawo ni a ṣe yan an si ipò yii?
3. Ki ni ipò Aarọni ati Miriamu?
4. Ki ni ẹṣẹ Miriamu ati Aarọni?
5. Bawo ni Ọlọrun ṣe fẹ ki a huwa si awọn alufaa wa?
6. Ki ni ṣẹlẹ si Miriamu nitori èṣẹ rẹ?
7. Mose ha dá a lẹbi bí? Ki ni ohun ti ó ṣe fun un?
8. Bawo ni a ṣe mọ pe Miriamu ati Aarọni ronupiwada?